| TINUBU FỌMỌ YỌ | TINUBU EXCELLED |
|---|---|
| Ìròyìn ọmọ Tinúbú tún gbòde | News of Tinubu's son is all about town |
| À ní ẹ tẹ́tí gbọ́ | Kindly listen attentively |
| Ohun tÁṣiwájú fọmọyọ lé lórí | The deeds of Asiwaju that make him stand out |
| Ó dáa kó yé gbogboo wa, | Deserve our attention and understanding, |
| Mo ní lásán kọ́ la sọ ọ́ dorin; | It is not in vain that this has been turned into song; |
| Ìròyìn Èkó yẹ ní títànkálẹ̀. | Reports about Lagos deserve being disseminated. |
| Ẹ̀yin ọmọ Nàijíríà! | Nigerians! |
| Bí ẹ bá ń wá akọni òṣèlú | If you seek an accomplished politician of |
| Tó gbóuńjẹ-fẹ́gbẹ́ tó gbàwo bọ̀ | note |
| Tinúbú lakọni ọmọ tó dángájíá – | Tinubu is an outstanding patriot – |
| Tó ṣiṣẹ́ takuntakun; | Who has done so much; |
| Àìmọye ìtẹ̀síwáju tó mú wọ ìpínlẹ̀ Èkó yíkáyíká, | The immeasurable progress he brought to the whole of Lagos State, |
| Ẹnikẹ́ni tó bá rebẹ̀ | Anyone who has been to Lagos |
| Ló lè sọ ribiribi iṣẹ́ tÁṣiwájú ṣe fún wọn; | Can testify to the great things he has done; |
| Ìràwọ̀ ọ̀sán tó un tágbàlagbà ń sápẹ́ sí | Even elders will marvel at daylight star |
| Erin tẹ́ranko, ẹ̀gàn ló kù. | Gangantuan indeed is the elephant, save for mischief. |
| Àwọn iṣẹ́ tí Bọ́lá Tinúbú ti ṣe | The great accomplishments of Tinubu are evident |
| Àìrìnjìnnà làìrábuké ọ̀kẹ́rẹ́ | Only the unadventurous fail to discover marvels |
| | If indeed we wander enough we may discover a squirrel with hunchback; |
| Gbogbo ará Èkó mọ̀ pé rẹ́rẹ́ rún | All Lagosians know that much has been done |
| Bó bá jẹ́ bí wọn tí ń ṣèjọba | As far as governance is concerned. |
| Ètò ìjọba tó múná dóko ló ṣe | He has set the pace in good governance |
| Kò sí ibí tí kò gbin igi ìtẹ̀síwájú sí | He has planted the seed of development everywhere |
| Ó tọ́ ká sọ díẹ̀ níbẹ̀: | It is fitting that we acknowledge some of these. |
| Ohun táráyé fi ń mọ aṣáájú tó ní láárí | The hallmarks of a good leader |
| Tó dáa, tó fọmọ yọ. | Who shines by excellent performance |
| Òun lànfààní tó bá ń tọwọ́ ẹ̀ ṣàn kìri ìlú; | Are those public benefits emanating from him. |
| Bí Bọ́lá Tinúbú ti ṣe yàtọ̀ gbáà nù-un, | That is what marks Bọla Tinubu out, |
| Ìjọba tó lóore ńnú ló fọjọ́ gbogbo ṣe, | He has all along been running a beneficent administration, |
| Bí ẹ dé gbogbo agbègbè tó jẹ gómìnà lé | This much is evident everywhere in his |

| | |
|---|---|
| lórí, | domain |
| Bó ṣelé ṣoko, | Whether at home or on the farm |
| Àtọba atìjòyè tó ń bẹ níbẹ̀ ní ó ròyìn. | Monarchs and chiefs around would testify to this. |
| Ọ̀pọ̀lọpọ̀ ibi tÁṣíwájú gbin igi ìtẹ̀síwájú sí | I visited as many places as bear Asiwaju's stamp of progress |
| Mo débẹ̀ mo wòran gan-an ni; | To see and observe! |
| Ó dáa ká fi gbogbo ẹnu kí Bọ́lá kú iṣẹ́ ni: | It's only right to bid him "Well done". |
| Òun gan-an sì labàmì òṣèlú, | He is the rare politician that spends public |
| Tó fowó ìlú rànlú lọ́wọ́, | funds for public good |
| Iṣẹ́ ńlá-ńlá tó ṣe káàkiri | For all the mighty projects he undertook across the State |
| Èmi ò mọ tẹni tó tún fẹ́ gbórín jurúu wọn | I do not know of any politician who |
| Èmi ò mọ bi òṣèlú tún ti dábírà bẹ́ẹ̀. | achieved such a feat anywhere. |
| Bọ́lá Tinúbú ni mo mọ̀ láṣíwájú | Bọla Tinubu is the one I know as the leader[1] |
| Bó bá jẹ́ ti ká mú ànfààní kárí, | Whether it is about fostering development |
| Tó ṣe wí pé gbogbo òṣìṣẹ́ abẹ́ ẹ̀ ló ṣèrànlọ́wọ́ fún | To the extent of assisting all workers |
| Ẹni táráayé ń tara rẹ̀ dìde ni | He is one person that supports others |
| Òun ni mo sì mọ̀ ní fọlárànmí òṣèlú, | And he is the humane politician that seeks |
| Tó jẹ́ pé ó fẹ́re fẹ́lòmíì. | the good of others. |
| Ẹ̀yin ọmọ aráyé, ṣé ẹ ti gbàgbé ni? | People, have you forgotten? |
| Lásìkò tí Bọlá Tinúbú ń polongo ìbò níjọ́sí | At the time Bọla Tinubu went on campaign |
| Ó lérí fún gbogbo ará ìpínlẹ̀ Èkó pátápátá; | He pledged to all citizens of Lagos State |
| Pé lọ́gán tó bá wọlé gbogbo Èkó ní ó dàkọtun; | That as soon as he won and took the reins of government,<br>All of Lagos State would come anew; |
| O sọ un tó fẹ́ẹ́ ṣe fún wọn gangan; | He reeled out the programmes he had for them |
| Èkó dìbò fÁṣíwájú tán ká wí kẹ́ ẹ gbọ́; | Lagosians voted in Asiwaju and I can aver |
| Gbogbo ọ̀rọ̀ ìlérí ló mú ṣẹ létò létò. | That all his campaign promises were systematically fulfilled. |
| Gbogbo ohun tó fọwọ́ sọ̀yà lé lórí | All the various issues on which he pledged |
| Wọ́n jẹ́ mímúṣẹ, láìsí àwáwí rárá; | Were faithfully fulfilled without excuses |
| Ká fami, ká faná, ká wọkọ̀ nírọ̀rùn, | Provision of water and electricity<br>As well as transportation without stress, |
| Etò ìlera tó ní láárí | Good and reliable healthcare delivery system |
| Mímú ló mú wọn lẹ́sẹẹsẹ | All these he rolled out in turns |
| Tíṣẹ́ ń lọ ní pẹrẹwu; | Such that work proceeded in full swing |
| Gbogbo afínjú ṣiṣẹ́ làkọ̀tun àtàyíká tó mọ́ | Enforcement of hygienic living practice and clean environment |
| Títí dórí títì lílà. | Together with construction of reliable roads. |
| Àwọn ilé olówó pọ́ọ́kú pọ́ọ́kú kíkọ́, | As for the low-cost housing scheme |

Bọ́lá rọ́jú ṣe kíṣà sí i;
Ètò àti gbowó orí,
Ọpọlọ lAṣíwájú  fi ṣe é gbangba –

Ó kájú iṣẹ́ gan-an ni;
Àwọn pẹ̀gàn pẹ̀gàn, ẹnu wọn á sì wọ wòwò!
Ẹ máa gbọ́:
Ẹnu ọ̀tá ó wọ wòwò lásán
Aṣíwájú ló gbárà míì dé táráyé n ṣápẹ́!

Ribi ribi iṣẹ́ tó ṣe nípa ètò ẹ̀kọ́ tó yè kooro,

Ká rísẹ́ ṣe, ká róunjẹ jẹ;

Ó múṣẹ́ ṣe, ó fọmọ yọ;
Ọ̀kúnkúndùn ló bá wọn mú gbogbo ètò ìmóríyá,
Ó dúró déédé,
Ojú àánú sì pọ̀.
Isẹ́ tí Bọ́lá Tinúbú ti ṣe,

Èèyàn ò leè ṣàlàýe irú ẹ̀ ní ṣókí lásán,
Sísọ lérèfée ò sì ràn án rárá,
Ká kúkú ṣíṣọ lórí rẹ̀ lọ́kọ̀ọkan:
Òun ni mo fi fẹ́ẹ́ mú wọn lẹ́ṣẹẹsẹ,
Àwon ọ̀nà ẹ̀kúnrẹ́rẹ́ ló dáa ká gbà láàyè gbáà.

Àwọn kókó, kókó tí mo kọ́ tì síwájú

Mo dọ́gbọ́n mo fi ṣe palẹ̀ ọ̀rọ̀ mọ,
Ká rọra mọlé lórí ẹ̀ ló kù –
Ìpìlẹ̀ ló dúró fún;
Ohun tó mú Bọ́lá Tinúbú fọmọyọ

Ìròyìn Èkó tí ò farasin kúkú ni;
Àtọba àtìjòyè ló tó kó gbọ́ ọ níbòmíì.

Ẹ ẹ̀ rí i, ìyà tí ń jará Ẹko lọ́jọ́ pípẹ́ ni mọ́tò wíwọ̀,
Ìgbà tÁṣíwájú wáá dé, ó ti fẹ́ẹ́ sọ Èkó dìlú ọba,
Ó kó pánúmọ́  ńlá ńlá wọlé rẹpẹtẹ,
Àwon ọkọ̀ bọ̀gìnnì-bọ̀ginnì tí wọ́n fi ń kérò

In this respect Bọla did wonders;
On effective taxation
Asiwaju clearly applied sense and knowledge;
He was certainly equal to the task –
Such that all detractors were silenced!

Please note that
Detractors were not just silenced
It was Asiwaju that brought bewildering innovations
Which kept the populace applauding
His excellent work on a sound educational system
Employment opportunities and provision of food
These he embarked upon and excelled in;
He made the people's welfare his priority

He is quite faithful –
And indeed very humane
The magnitude of the work that Bọla Tinubu has done
No one can recall such things in passing

---

As brief recounting won't do at all
Let's then unveil them one by one:
Hence I wish to list them step by step
A detailed account is the ideal way to explain.

The key points which I earlier touched upon
I cleverly used them to summarize
What remains is to build fully on them.
As they provide a very solid foundation;
What accounts for Bọla Tinubu's exceptional record
Is well known to all
Both kings and dignitaries in other lands must hear this.
You all know that  inhabitants of Lagos
Had transport problems for long
But Asiwaju has almost turned Lagos
Into the land of the Queen[2]
He imported many long buses
The buses that they now use to move

| | |
|---|---|
| kiri Èkó, | commuters all over Lagos |
| Ó kó wọn dé pẹ̀lú ètò. | He brought them in a systematic manner. |
| Ẹnikẹ́ni tó bá mọ ètò tó ṣe lórí àwọn ọkọ̀ wọ̀nyí, | Whoever knows the plan for these buses |
| Tí wọ́n fabala títì sílẹ̀, tó ń múṣẹ́ yá, | That have been allocated a dedicated line |
| Ọpọlọ pípé pé ré ni wọ́n fi ṣètò ọ̀hún – | They are deploying incredible wisdom in running the programme |
| Ó wúlò jọjọ fáráyé – | And the public is benefiting from it |
| Ó dáa dọ́ba; | It is so wonderful |
| Àwọn ò sì rí bíi móòluẹ̀ rárá, rárá, | And they are not like the old fashioned *móòluẹ̀*[3] |
| Gbogbo ayé ló ń wọkọ̀ ní rọ̀rùn. | Everyone moves about in the buses with ease. |
| Ẹ tún máa gbọ́ mi: | That is not all. |
| Ètò ìmọ́tótó ni sábàbí afínjú – | Cleanliness is the mark of the decent |
| Aṣíwájú Bọ́lá Tinúbú ti sÈkó di mímọ́; | Aṣiwaju Bọla Tinubu has cleaned up Lagos |
| Gbogbo ibi tá a ti ń lémú níjọ́sí | All the dirty and stinking parts of old |
| Wọ́n ti mọ́ kadara! | Are now sparkling clean |
| Gbogbo àkìtàn ló parẹ́ láàrin Èkó, | He has eliminated rubbish dumps in Lagos |
| Bọ́lá ṣe kísà níbẹ̀. | Bola has indeed done wonders in these places |
| Ìgbìmọ̀ aláfínjú ló kọ́kọ́ faṣẹ́ ìpalẹ̀ ìdọ̀tí mọ́ lé lọ́wọ́ | He first empowered an environmental taskforce to clear refuse |
| Gbogbo ẹni tó bá mÈkó ijọ́sí bíi tí i rí, | Those who knew what the situation was in old Lagos |
| Gbogbo yín pátá, | All of you without exception – |
| Ẹ kálọ wÈkó àkọtun, | Come down to see the new Lagos |
| Kẹ́ ẹ jẹ́ ká wo un tÁṣíwájú fọgbọ́n ṣe, fọpọlọ ṣe; | And appreciate what Aṣiwaju has wisely and brilliantly done |
| Ìdọ̀tí ti dọ̀rọ̀ ìtàn lábẹ́ẹ ‘kérénì’. | Dumping of refuse under the bridge is now a thing of the past |
| Gbogbo ibi wèrè ń dúró si ti mọ́ gbáà, wọ́n dìyàtọ̀! | What used to be havens for lunatics have now been cleared and are totally different |
| Ẹni tó bá fẹ́ já mi, | Whoever wishes to contradict me on this |
| Kó ṣèbẹ̀wò kiri Èkó; | Should embark on a tour across Lagos |
| Kó wá máa kíyèságbègbè, àyíká; | Let him observe neighbourhoods and environs |
| Bó bá tún ṣe | And thereafter |
| Kó wo gbogbo ẹsẹ̀-kùkú káàkiri; | Let him also observe the surburbs |
| Ìròyìn ò tó ká fojú kàngboro Èkó fún mímọ́ tóní – | Mere reports are less convincing Than the actual viewing of Lagos metropolis for its cleanliness |
| Fún mímọ́ kadara – | For its sparkling cleanliness |
| Fún dídùn ún wò. | And its sheer aesthetic beauty! |
| Ìlú tí ẹ bá ti wọ̀, | Any town or city that you visit |

| | |
|---|---|
| Tó bá ti jẹ́ kìkì ẹ̀gbin, kìkì ìdọ̀tí, | Where filth and garbage fill the place |
| Aṣáájú tó wà níbẹ̀ ló rírí, | It is the leaders there that are dirty |
| Aṣáájú tó bá láfínjú níbi kíki | Anywhere leaders imbibe the spirit of cleanliness |
| Àyíká ni yóo ṣèròyìn ìjọba ìlú fáráyé, | The environment speaks well of them |
| Ká wá gbólórí tí ń bẹ níbẹ̀ lórí òsùnwọ̀n. | Let the surburbs publicize to the world a government |
| | So we can place the leaders on assessment. |
| Ìjọba Bọ́lá Tinúbú ti palẹ̀ ìdọ̀tí mọ́ láú! | Bọla Tinubu's government has cleared up all filth |
| Bí imí, bí èèpo ọ̀gẹ̀dẹ̀, bí ewé, bí ọ̀rá ò sí ní pópó mọ́; | Human waste, banana peels, leaves and nylon no longer litter the road |
| Ohun tí wọ́n fi rọ́pò wọn kò sì tayọ mímọ́ tóní, | What has replaced them is absolute cleanliness. |
| Mímọ́ kangá kadara; | Only the damned filthy can thrive in foul |
| Àwọn ọ̀bùn ràìràì ló le gbénú òórùn! | odour! |
| Aṣíwájú Bọ́lá Tinúbú ti ṣètò ìmọ́tótó | Aṣiwaju Tinubu has organized environmental sanitation, |
| Tó ṣe wípé kò tiẹ̀ fàààyè gbọ̀bùn rárá, rárá; | Making cleanliness the priority of government |
| | Such that gives no room for the filthy; |
| Bọ́lá ti mÈkó dùn-ún rí lójú, | Bọla has made Lagos a showpiece |
| Bó bá ti jẹ́ ti pipalẹ̀mọ́ ẹ̀gbịn, | In terms of water and refuse disposal. |
| Tinúbú ló fọmọ yọ, tó gbáfínjú wọṣẹ́ ọba, | Tinubu is the pace-setter in sanitizing the public service; |
| Àkànbí tó fọpọlọ dábírà ságbègbè! | Akanbi intelligently transformed the state. |
| Ilé iṣẹ́ to fẹ́ẹ́ máa fi pàǹtí ṣajílẹ̀ lọkọ Rẹ̀mí tún gbé wá! | Rẹmi's husband also brought in a waste-to-manure production company! |
| Tó jẹ́ pé ká máa kó pàǹtí dànù ò ní sí mọ́, | So that refuse disposal will no longer be necessary |
| Ká máa tún ta pàǹtí fúnjọba, ká tún gbowó ni | It is just a matter of exchanging refuse with government for cash! |
| Òun sì lara ètò àràmọ̀ndà tÁṣíwájú fi lọ́lẹ̀, | It is part of the wonderful projects that Asiwaju initiated |
| Tí i múlé ayé rọgbọ, | Towards making life much more comfortable |
| Pàǹtí dowó ni ó dà ní gbẹ̀yìn ọ̀rọ̀. | The outcome in the end will be waste-to-wealth! |
| Gbogbo ibi tÁṣíwájú faná sí, | We diligently toured places where Aṣiwaju |
| Fínnífínní la kíyè sí i: | provided electricity for verification |
| Ẹ̀rọ tó ń fúnná lágbára tó pín kiri; | The transformers which he distributed all over |
| Ọ̀pọ̀ òpópóoná rírì kiri agbègbè tó bá tún níná, | And so many electric poles erected<br>In other areas with electricity supply |

| | |
|---|---|
| A kiri títí, a rírú rẹ̀ lẹ́yìn ibi tí i jOwódé Onírin. | We went far and found such behind Owode-Onirin |
| | |
| A sì tún dé Ọmọ-Ọlọ́gẹ̀dẹ̀, | We also reached Ọmọ Ọlọgẹdẹ |
| A wàrà tó dá | And saw the wonders he performed |
| Ká tó wá lọ sí Èyítà. | Before proceeding to Eyita. |
| | |
| Àwọn ibi tó tún gbé ‘Tiransifọ́mà’ ńlá-ńlá sí, | The places in which he installed giant transformers |
| Nínú oko ẹja tó wà nÍkòròdú, | In the fish farm at Ikorodu |
| Ó wú wa lórí, a tún re Bọ̀rọ̀kìnní-àgá, | We were impressed and also visited Bọrọkinni-Aga |
| Tí wọn tí ń tanná rokoso! | Where they generate electricity. |
| A à sì gbàgbé ká ya Solómádé! | We did not forget to visit Solomade. |
| Bó bá jẹ́ pé ká má a sọ ọ́ lọ, | If we were to keep on enumerating |
| Ọ̀nà tó pín wọn sí pọ̀ púpọ̀. | The places he distributed them, they are indeed many. |
| Bó bá jẹ ká sọ nípa kàngá dẹ̀rọ̀ ìgbàlódé, | Were we to talk about modern boreholes, |
| TAṣíwájú pọ̀ lágbègbè Èkó yíkáyíká, | Aṣiwaju sank so many around Lagos; |
| A kúkú mójú kanrú rẹ̀ lÁlákùkọ, | We actually saw the very type at Alakukọ |
| Tí gbogbo ẹ̀ si jọni lójú ní bíntín, | And in all, we were greatly amazed. |
| Ó rọ́jú fa kíki; | |
| A gbìyànjú, a délé ìwé Abẹ̀sà tó kúkú ńbẹ níbẹ̀ náà. | We also managed to reach Abẹsan School located therein. |
| | |
| Báráyé bá ń sọ nípa ètò ìlera, | Talking about free health service |
| Ètò tó mọ́yán lórí ń bẹ níbi kan jù kan lọ | Some places enjoy it better than others |
| Ètò lètò ìjọba Èkó | The scheme of the Lagos State Government stands out |
| Gbogbo ẹni tó bá débẹ̀ ní ó sì mọ̀ pérọ́ kọ́; | Everyone who has been there will testify that it is no joke |
| TAṣíwájú Bọ́lá Tinúbú ni mo mọ̀ lójúlówó ètò ìlera, | I can say that the scheme of Asiwaju Bọla Tinubu is genuine |
| Àwòkóse lọ̀rọ̀ Èkó jẹ́, | Lagos has set the pace |
| Ẹni tó bá wù kó gbà! | Whoever wants may dispute this. |
| | |
| Ibi tí Bọ́lá Tinúbú ti rìn dé lórí’ṣẹ́ ìlera | Bọla Tinubu has advanced in providing health service |
| Àfẹni tó bá rítú tó pa ló lè sọ: | Those who have seen his exploits can confirm |
| Ikẹja ‘jẹ́nẹ́rá họsipítù’ tẹ́lẹ̀-tẹ́lẹ́ẹ́-rí | The old Ikeja General Hospital |
| Ó ti yípadà – | Has now been upgraded |
| Ó sì ti lórúkọ tuntun; | And now has a new name |
| Ó ń jẹ́ ‘Lagos State University Teaching Hospital’ | It is now Lagos State University Teaching Hospital |
| Ní kúkúrú LASUTH! | Or LASUTH, for short. |

| | |
|---|---|
| Ohun tAṣíwájú jẹ́ ko dí yíyí padà sí, | Aṣiwaju caused it to be upgraded |
| Tó fi dilé-wòsàn ńlá, | To make a bigger hospital-- |
| Tó ńkọ́ni lẹ́kọ̀ọ́ ìṣègùn ẹ̀kúnrẹ́rẹ́, | A centre for advanced medical training |
| Ibi tí wọn tí ń gboyè oníṣẹ́ ìṣègùn gan-an ni; | Where people graduate as doctors; |
| Ìgbà tí mo débẹ̀ | When I got there |
| Mo mọ̀hà tÁṣíwájú kọ sí Nàìjíríà. | I gained insight into Aṣiwaju's vision for Nigeria |
| | |
| Ẹni tó bá wá dé ilé-ìwòsàn ìjọba Èkó tí mo wí un, | Whoever gets to the hospital that I am talking about |
| Àràbarà ni tilé ńlá-ńlá ilé tuntun-tuntun, | Will discover that it is magnificent, with mighty and new structures |
| Ẹ̀ka-jẹ̀ka àìsàn tí ń ṣọmọ Áadámọ̀ ló wà pátápátá! | It has various units for diverse human ailments |
| Gbogbo irinṣẹ́ tí ń múṣẹ́ yọ lẹ́ka kọ̀ọ̀kan, | All the equipment to facilitate the operation of each unit |
| Àwọn ẹni tíṣẹ́ dá lójú ló ń bẹ níbi gbogbo, | Competent hands to handle every section |
| Kò sì sírú àìsàn tó tọ́ ka máa gbé lọ ilẹ̀ òkèèré mọ́, | And there is no reason to travel abroad for medical treatment any longer |
| Bọ́lá ló ṣe kísà fórílẹ̀-èdè. | Bọla has done wonders for the nation. |
| | |
| Ẹ̀ka tí wọ́n tí ń tọ́jú aláìsàn líle, | The department that handles serious cases |
| Níbi ẹ̀mí bá gbé fẹ́ẹ̀ẹ̀ bọ́, | With people who are almost dying |
| Ó ṣe ni lójú firí, ọ̀rọ̀ àpárá kọ́, | It is unbelievable |
| Iṣẹ́ tí wọ́n ń ṣe nípa ìgbàlà ẹ̀mí wá á hàn kedere, | It is a serious matter<br>Their efforts at saving lives are evident |
| Ẹ̀mí tó kọjá kó tó rìn jìnnà, | They are able to bring the dying |
| Wọ́n tún ń rí wọn jí padà níbẹ̀! | Back to life. |
| | |
| Gbogbo ẹ̀rọ gidigidi tó máa ń ṣèrànlọ́wọ́ fún mímí | I saw expensive machines |
| Mo ti máa ń gbọ́ nípa rẹ̀ tẹ́lẹ̀-tẹ́lẹ́ẹ̀rí, | That I only used to hear about |
| Ibi tí wọ́n gbé fi ń ṣiṣẹ́ gan-an, | Being put to use |
| Èmi sẹ̀sẹ̀ rí i ni; | |
| Ẹ̀rọ lẹ̀rọ ìgbàlà ẹ̀mí - | Think of the life support machine |
| Tí ń bẹ nílé ìwòsàn ìjọba Èkó, | At the hospital run by the state government |
| Dájú dájú mo ti rí kísà ńbẹ̀! | No doubt, I have seen wonders there |
| | |
| Ẹ̀rọ gbogbo tí wọ́n fi ń ṣiṣẹ́ ìgbàlà àwọn ẹ̀mi tó bá fẹ́ẹ̀ẹ̀ bọ́ | Life-saving machines needed to save people that are almost dead! |
| Bọ́lọ́jọ́ bá dé gan-an ló kù, táìsàn ò níí gbọ́ títọ́jú; | Only in rare cases do patients die |
| Dájúdájú iṣẹ́ẹ ṣòkúdàáyè gan-an niṣẹ́ tí wọ́n ń fi wọ́n ṣe; | Certainly, death-to-life operation is their main preoccupation |
| Ọ̀kan ṣojú mi; | I was witness to a case. |
| Mo sì fọba òkè tó dá gbogbo aráyé ṣẹ̀rí ọ̀rọ̀! | And the Almighty God is my witness. |

| | |
|---|---|
| Ẹ̀ka tí wọ́n ti ń tọ́jú ojú nílé ìwòsàn ìjọba Èkó, | The eye clinic at the Lagos State Hospital |
| Ó ti kúrò ní 'wàsáa' tí ń jéré | Has witnessed remarkable development |
| Gbogbo ojú tó fẹ́ fọ́, ojú tí ń ṣépín, | All partially blind eyes, all those secreting |
| Àfiṣẹ́yìn ni, téégún ń fiṣọ. | Are coming back to life |
| Kí ojú ó maa sin tàlùbọ̀, | Eyes afflicted by cataract |
| Bójú fẹ́ ojú lè maa ta bàbá | Or those perpetually blinking |
| Kólójú ó gbójú lọ síbẹ̀ ló kàn kù. | Only need be taken there for treatment. |
| | |
| Ọ̀fẹ́ tí wọ́n ń tọ́jú ojú fún gbogbo èèyàn ìlú, | The free eye treatment offered to the populace |
| Nínlá nínú iṣẹ́ àánú ló jẹ́, | Is a vital act of charity |
| Bójú bá jẹ mọ́ṣẹ́ abẹ, | Whenever operation is deemed absolutely necessary, |
| Wọn a sì yọ kòkòrò dànù lójú fótí! | Promptly is the diseased eye corrected |
| Bó jẹ́ dínngí lojú gbà níbẹ̀ – | In cases requiring recommended glasses |
| Ọ̀fẹ́ ló tún jẹ́! | These too are offered free of charge |
| Dínngíi Bọlá ni gbogbo ìlú mọ̀ - | Bọla's glasses are popular with the people |
| Òògùn ojú kíkán sójú fún kálukú, | Even provision of eye drops for everyone's use |
| Ara oore tÁṣíwájú ṣe wọ́n ní; | Is part of Asiwaju's welfare package, |
| Ètò ìlera pàtàkì bíi irú èyí yàtọ̀ sàrà-ọ̀tọ̀! | A healthcare scheme of this kind is special and unique. |
| Gbogbo ẹ̀rọ tí wọ́n fi ń ṣàyẹ̀wò, | All equipment needed for diagnosis |
| Tí wọ́n fi ń tọ́jú ojú, | As well as those for eye treatment |
| Wọ́n pọ̀ níbẹ̀ rẹkẹtẹ | Abound there; |
| Akọ́ṣẹ́-mọṣẹ́ ni gbogbo òsìṣẹ́ tí ń bẹ níbẹ o jàre, | All cadres of personnel are certified professionals |
| Gbogbo wọn kọ́ṣẹ́ ojú ni, | They are proven eye specialists |
| Ọba òkè ló ń fún wọn ṣe | They are enabled by God Almighty |
| Tójú kan ò sèèsì fọ́ mọ wọ́n lọ́wọ́ rí, | And have not had a single record of accidental eye loss |
| Ká dúpẹ́ ò léèwọ̀. | Giving thanks for this is certainly not out of place. |
| | |
| Eni tó bá tún dé ilé ìgbẹ̀bí ńlá, | Whoever gets to the new maternity |
| Tó ń bẹ ní pópó 'Kambẹl' Èkó | That Asiwaju built |
| Titun tÁṣíwájú ti túnbẹ̀ ṣe, | Along Campbell Road in Lagos |
| Àrà ọ̀tọ̀ gidi ló jẹ́ | Will see another wonder |
| Ó kúkú sọ ọ́ di tuntun gan-an ni; | He simply upgraded it |
| Gbogbo àwọn ohun èlò, | With every major facility |
| Bí irinṣẹ́ẹ̀lera pàtàkì | Like special health machines |
| Tí i múṣẹ́ dán mọ́rán | Which accelerate the pace of work |
| Ó ti kó wọn dán mọ́rán | All these are provided in full. |
| Ó ti kó wọn dà síbẹ̀. | |

| | |
|---|---|
| Aṣíwájú Bọ́lá Tinúbú, | Asiwaju Bọla Tinubu |
| Tó ṣiṣẹ́ àánú títíí tí, | Extended his kind deeds |
| Tó ní gbogbo ohun ẹlẹ́mìí làá mójú tó; | To caring for all living things |
| Bọ́lá Tinúbú ni mo mọ̀ tó kọ́lé ìwòsàn ẹranko, | Bọla Tinubu is the only one that I know<br>Who has built a veterinary clinic |
| Àkọ́kọ́ irú ẹ̀ tí mo rí ní gbogbo ilẹ̀ èèyàn dúdú | The first of its type in Africa |
| Ká tóó wá sọ pé gbogbo Nàìjiria. | Not to talk of Nigeria. |
| | |
| Mo dénúulé ìwòsàn ẹranko tí Bọ́lá Tinúbú kọ́ | I went into the veterinary hospital that Bọla Tinubu built |
| Mo lọ wòran àmọ̀dájú, | Just to see things for myself |
| Mo rí kísà tó jọ̀ọ̀yàn lójú, | And I saw wonders |
| Wọ́n pín títọ́jú ẹranko sẹ́lẹ̀ka-jẹ̀ka ni - | They have different units to care for animals |
| Àràbarà ni bẹbẹ tÁṣíwájú ṣe fẹ́ranko | What Asiwaju is doing with animals is amazing |
| Àfi bí ilé ìwòsàn ọmọ ènìyàn gẹ́lẹ́, | It is just like a place to care for human beings |
| Ẹni ó bá dé bẹ̀ ní ó ròyìn. | Only those who have been there can testify. |
| | |
| Ẹ̀ka tí wọ́n ti ń sàyẹ̀wò ẹ̀jẹ̀ ń bẹ: | The laboratory unit in the hospital |
| Ẹ̀ka tí wọ́n ti ń ṣe àyẹ̀wò àìsàn tó ń ṣẹran, | And the unit for communicable diseases |
| Láti fi mọ̀tọ́jú tó bá tọ́, | Help guide treatments |
| Ibi ti wọ́n ti ń gba ìtọ́jú fẹ́ran, lọ̀tọ̀ ni; | There is a separate pharmacy for animals |
| Ọ̀tọ̀ nibi tí wọ́n ti ń ṣiṣẹ́ abẹ– | And a surgical unit for animals! |
| Tó bá jẹ́ pó jẹ mọ́ṣẹ́ abẹ | |
| Ààyè tẹ́ranko ń sùn tí wọ́n bá dúró | There is a ward for those on admission |
| Gbogbo ẹ̀, gbògbò ẹ̀ ní ń bẹ níbẹ̀ gbá à! | All these are put in place |
| | |
| Àwọn ẹranko bí ewúrẹ́, àgùntàn, àgbò, | Goats, sheep and rams |
| Bí i kẹ́tẹ́kẹ́tẹ́, màálù, ràkúnmí, | Asses, cows and camels, even down to |
| Títí dórí ajá, ọ̀bọ, àtẹṣin; | Dogs, monkeys as well as horses |
| Láyé Tinúbú, gbogbo ẹranko tún ṣoríire, | The administration of Tinubu |
| Àwọn ẹranko tó bá ṣe pé wọ́n pọ̀ | Has given animals a new lease of life |
| Wọn ò lè wá fún títọ́jú, | They treat animals that are too many |
| Wọ́n ń ránṣẹ́ lọ síbi tí wọ́n wà fúnwòsàn! | To be brought to the hospital from wherever they are |
| Báráyé bá ń wẹ̀ni tó ṣàṣeyege, | When people are in search of an accomplished person |
| Àṣeyege nínú iṣẹ́ jura wọn lọ; | There are various levels of accomplishment |
| Ọdẹ tó règbẹ, | A hunter that goes hunting |
| Tó perin, pẹfọ̀n, pa jàkùnmọ̀, | Killing elephant, bushcow, wild cat |
| Pàgbọ̀nrín, pa líìlí, paran kúnnúgbá; | Antelope, tree-bear and hartebeeste |
| Ṣé déedé ọdẹ tó peku, tó pa gàrè, tó sì pakerese lásán ni? | Is not to be compared with another who kills mere rat and smaller prey |

| | |
|---|---|
| Bí wọ́n bá pé ká fọ́dẹ lóyè– | If such hunters were to be honoured |
| A à  le fi wọ́n wéra wọn; | These surely cannot be compared |
| Ȁgbà oyè lọdẹ aperin, pẹfọ̀n, pa jàkùmọ̀. | The chief hunter is the killer of elephant, bushcow, wild cat |
| Lọ́jọ́ pípẹ́, pípẹ́ | In days gone by |
| Gudu-gudu méje àti yà yà mẹ́fà là ń gbọ́: | We heard of various astonishing accomplishments |
| Bí lágbájá bá ṣẹ wọ́n | If anyone ever achieved such feats |
| Ȍun sì lọmọ aráyé ń ṣe bí ọba | He was treated by the world like a king. |
| Àìmọye ni gudugudu àti yààyà, | Countless indeed are various astonishing feats |
| Èyí tÁṣíwájú ṣe níṣẹ́ẹ̀jọba Èkó, | Which Aṣiwaju achieved in the governance of Lagos |
| Wọ́n tóo mú kọ́gbọ́n – | They are all worthy of emulation |
| Ọgbọ́n ò ṣe tẹnìkan; | As wisdom is no individual's  monopoly |
| Èèyàn ò lè ka gudugudu àti yààyà ọ̀hún tán, | Nobody can wholly enumerate his achievements |
| Kẹ́légbẹ́ ó mẹgbẹ́ ẹ̀ ló kù. | Let every rival know his proper route. |
| Ẹ jẹ́ ká bojú wobilé kíkọ́, | Let us for a moment consider the housing project |
| Tó jẹ́ pÁṣíwájú fi dábírà kiri Èkó  ni; | A project with which Aṣiwaju has done wonders all over Lagos |
| Àkànbí ṣe bẹbẹ - | Akanbi[4]  has performed impressively |
| Ó fẹ́ kẹ́lòmíì ó nílé lórí; | He wants to see others sheltered |
| Ilé olówó pọ́ọ́kú tó ti kọ́ kalẹ̀ ní 'fúláàtì'; | He has built low-cost houses. |
| Mo rebi tí wọ́n kọ́ wọn sí gangan, | I went to the very place where they built them |
| Èèyàn tó bá ni débẹ̀ ní ó ròyìn. | Anyone who goes there will have something to report. |
| Àwọn ibi tó kọ́lé táa wí wọ̀nyí sí, | The areas where he built these houses |
| Wọ́n ń bẹ lÁlágbàáà, | Include Alagbaa, |
| Ọ̀nà ò kúkú rújú | straight on to |
| Bi wọn ti ń bẹ lÓjókòro, ni wọ́n tún ń bẹ lÓko-ọba, | Ojokoro as well as Oko-Oba |
| Tòkè Eléètú kúkú ń bẹ bí omilẹgbẹ, | And those at Oke Eleetu are plentiful |
| Mo ṣèbẹ̀wò rebi i ti Sàsá, | I paid a visit to Sasa |
| Mo lọ rí kísà ńbẹ̀ | And saw wonders there. |
| Àwọn ilé olówó pọ́ọ́kú-pọ́ọ́kú | Decent low-cost houses |
| Tó ṣe pé bí ìwọ̀n-eku-ìwọ̀n–ìtẹ́ ni | Designed to suit individual pockets |
| Aṣíwájú kọ́ irú wọn fáráyé, wọ́n lọ kánrin! | Asiwaju built these for people in large numbers! |
| Tó sunwọ̀n àwọn ènìyàn tó jólówó ńlá. | Expensive ones are for the class of the rich |
| Ó tún kọ́ wọn sílẹ̀ náà fọ́lọ́lá; | These he provided to cater for the affluent; |

| | |
|---|---|
| Ó tún wá kọ́lé onípò tàárín – | Then too, houses for those in the middle class, |
| Tó ṣe wí pé rẹpẹtẹ ni wọ́n - | These he also provided in great abundance |
| Wọ́n lọ bí omi; | It’s appropriate to describe where he built them |
| Ó tọ́ kí n júwe agbègbè tó kọ́ wọn sí | |
| Ká kóyè méjì dànù. | So as to dispel any desire to doubt! |

| | |
|---|---|
| Ó yá! | Arise! |
| Ẹ jẹ́ ká jọ lọ sÁláúsá, Ikọ́ta, Bàdágìrì, Ìjọrá, | And let’s head for Alausa, Ikota, Badagry, Ijora, |
| Ayòbọ́, Adékúnlé, Makoko, | Then, to Ayobọ, Adekunle, Makoko, |
| Ìgbògbò, Bàrúwá, Oníwàyá, ká sì dỌlọ́kọ́nlá; | Igbogbo, Baruwa, Oniwaya, up to Ọlọkọnla; |
| Itú tí Bọ́lá Tinúbú pa, kàyééfì ni, | The feat Bọla Tinubu accomplished is incredible |
| Sùgbọ́n ẹ sá  jẹ n ṣàlàyé ibi tó tún kù, tẹ́ ò mọ̀: | Yet, let me describe other areas you don’t know. |

| | |
|---|---|
| Ẹ tún wá bá mí kálọ Ìmọ̀ta, Ìbẹ̀ṣẹ̀, Ọkọ́ta, | Come again with me to Imọta, Ibẹsẹ, Okota |
| Ìlúbìrin, Ìjáníkin, Amúwòó-Ọ̀dọ̀fin,Ògùdù; | Ilubinrin, Ijanikin, Amuwoo-Ọdọfin, Ogudu |
| Ká tún jọ dé Gbàgádà, Ìbẹ̀jú dé Lẹ́kí, | Let us as well head for Gbagada, Ibẹju, up to Lekki. |
| Ká dé Káninmọ́dò lọ wòran; | Let’s reach Kanimọdo to feed our eyes |
| Bùdó Ìpàtẹ ọjà la jọ fàbọ̀ sí lÁdó, | Then return to the tradefair complex at Ado |
| Kẹ́ ẹ lọ wo un tó mú tÈkó yàtọ̀. | So you can see what makes Lagos unique. |

| | |
|---|---|
| Ọ̀tọ̀ làwọn ilé tÁṣíwájú kọ́ sí Lẹ́kí, | Of different patterns are the houses Aṣiwaju built at Lekki |
| Tó jẹ́ pórúkọ Ọba Adeyinka Oyekan ló fi sọ | Which he named after Ọba Adeyinka Oyekan |
| Ọ̀tọ̀ ni tagbègbè Àjá | So are those in Aja named after Abraham |
| Tó jẹ́ pórúkọ Abraham Adésànyà ló ń jẹ́; | Adesanya |
| Bó bá rántí àwọn ẹni ìtàn | Whenever he remembers those historic figures |
| Ohun rere ló fi ń sọrí wọn, | He immortalizes them  by naming major projects after them |
| Ọ̀tọ̀ lèyí tó fi sọrí Àyángbùrẹ́ Ọba Ìkòròdú, | He named another after Ayangburẹn, the Ọba of Ikorodu |
| Sé Bọ́lá mọnú-ún rò púpọ̀. | Bọla is ever so thoughtful. |

| | |
|---|---|
| Àwon ilé tó tún kọ́ sínú ‘kọ́tààsì’ Ikẹja, | Bola built houses within Ikẹja Quarters |
| Àkànbí tún kọ́ wọn bẹ̀ẹ̀ ságbègbè Ìlúpéjú; | Akanbi did the same in Ilupeju area |
| Ó kọ́ sÉwú-Ẹlẹ́pẹ̀, | He also built some in Ewu-Ẹlẹpẹ |

| | |
|---|---|
| Ara àrà gidi tÁṣíwájú dá sórí ilé ni; | As part of the real wonders Aṣiwaju did on housing, |
| Kò sì gbàgbé àwọn Ìgbẹ̀sì, | And he did not neglect the Igbẹsi people too |
| Ó kọ́lé fún wọn níbẹ̀ náà. | By erecting houses for them as well. |
| Àwọn ilé tí Tinúbú kọ́, | The houses that Tinubu built |
| Ó kọ́ wọn ní ka-ò-dọ́gba: | Were erected according to earning capacity: |
| Ọ̀tọ̀ làáye awọn ọ̀gá | There are those for Executive Officers |
| Ó kọ́ tonípò kéékèèkéé, | And others for the junior cadre |
| Ó kọ́ tonípò tàárín, | He also provided for the middle ranks |
| Bóníkálukú bá ti ṣe lówó lọ́wọ́ sí nilé ti ń bẹ; | There are houses available in line with financial status |
| Àtonísẹ́, ọba àtọ̀tọ̀ọ̀kùlú nilé wà fún, | The houses are there for workers, chiefs and the elite |
| Kíkọ́ ló kọ́ wọn nísọ̀rí ọ̀tọ̀ọ̀tọ̀. | He built them all in different categories. |
| Àwọn ilé bíi yàrá kan pálọ̀ kan; | Houses ranging from one-bedroom flats! |
| Yàrá méjì pálọ̀ kan! | Two-bedroom flat! |
| Yàrá mẹ́ta pálọ̀ kan! | Three-bedroom flat! |
| Tòkè tilẹ̀! | To duplexes as well as bungalows |
| Wọ́n tún kọ́ ilé tó dá dúró, | |
| Gbogbo ẹni tílé bá ń wù lágbègbè Èkó pátápàtá, | For anyone desiring accommodation in Lagos and environs |
| Ẹnu kí kóó wá ó sanwó rẹ̀ | All you do is pay and collect the keys |
| Kó sì maa gba kọ́kọ́rọ́ ilé ni | |
| Bọ́lá Tinúbú ló fìkòkò sebẹ̀ fáráyé | Bọla Tinubu has made provision for the populace |
| Ilé wà nílẹ̀. | Houses are available en masse! |
| Ẹ̀yin ni ẹ lọ sílé iṣẹ́ ètò ìkọ́lé lAlausa | Just go to the Ministry of Housing at Alausa |
| Kẹ́ ẹ lọ rè é gba 'fọ̀ọ̀mù' tí wọ́n fi ń ralẹ̀, | For the application form to purchase yours |
| Ẹni tó bá fẹ́ẹ́ sanwó tiẹ̀  lẹ́ẹ̀kan ṣoṣo, | Whether you want to pay in full or in instalments |
| Mo fi dá kóówá lójú, ilé ń bẹ; | I assure everyone that houses are available |
| Bẹ́ẹ̀ náà lànfààní tún ń bẹ fún gbogbo èniyàn – | And there is an opportunity for those desiring to pay in instalments. |
| Tó bá fẹ́  maa sanwó díẹ̀ díẹ̀. | |
| Gbogbo ẹni tó bá fẹ́ nílé lórí, | All those wishing to have houses of their own |
| Kó jẹ́ wá ralé ìjọba; | You had better purchase a government-built house, |
| Ìjọba Tinúbú tí ṣoore ńlá lórí ilé gan-an ni; | Tinubu's government has done great favour on housing |

| | |
|---|---|
| A ṣẹ̀ṣẹ̀ fẹ́ẹ́ kọ́lé, | As for those just about to build, |
| Ká máa wálẹ̀ kiri ò sí mọ́, | There’s no longer need to search for land |
| Ẹni tó bá kó sálágbárí lọ́wọ́ rí, | Whoever had once fallen victim of fraudsters |
| Ó yẹ kó ti mọ̀ pélé ìjọba ló dáa yéye, | Should know by now that government house is safe to buy |
| Òun nìbàlẹ̀ àyà ń bẹ níbẹ̀ tó pọ̀. | It gives absolute peace of mind |
| | |
| Aṣíwájú Bọ́lá Tinúbú fọmọ yọ! | Asiwaju Bọla Tinubu has excelled |
| Ìgbà tó ṣíjú wo bí iṣẹ́ ètò ìdajọ | When he attended to the Ministry of Justice |
| Kíá kíá ló bá wọn túnbẹ̀ ṣe | He extended his reform to the sector |
| Àwọn adájọ́ wá bọ́ sínú ayé tuntun; | Ushering judges into a new era |
| Nípa gbogbo àwọn ètò ìmóríyá ti Bọ́lá gbé dé | Of the impressive programmes that Bọla introduced |
| Ẹjọ́ dídá ò falẹ̀ mọ́, yíyá ló ń yá; | The dispensation of justice has experienced a boost |
| Títún ló túnlé ẹjọ́ ṣe | The renovation of courts |
| Ànfààni adájọ́ àtàmofin ni; | Has been to the advantage of lawyers and judges |
| | |
| Ọ̀rọ̀ ẹnu ọ̀hún ọ̀rọ̀ àpárá kọ́ – | It is no empty claim |
| Ẹ sọ fún Gómìnà tó bá tun ṣe bíi tiẹ̀ kó sọ̀rọ̀. | Let any other governor who has a better record  talk |
| Bílé ẹjọ́ ti ṣe rí wùrù wúrú kò dùnmọ́ Bọ́lá ńńu, | Bọla was not pleased with the state of courtrooms |
| Ó kọ́lé ẹjọ́ ní tìgbà-lódé tuntun-tuntun | He therefore built ultra-modern courtrooms |
| Èèyàn tó bá délé ẹjọ́ Èkó  mọ̀ péṣẹ́ bíntín kọ́, | Those who have seen courts in Lagos can testify to this |
| Gbogbo ohun to múlé ẹjọ́ wuyì lábẹ́ òfin, | He has provided all that a court needs |
| Gbogbo wọn ló kó sílé ẹjọ́ kiri; | under the law |
| Awọn ohun èlò tí ń lọná, | Asiwaju has installed electronic facilities |
| Tí ó máa ń ṣètò ìdájọ́ ní yíyá, | All these Asiwaju provided in the court, |
| Gbogbo wọn lAṣíwájú ti bá wọn rà sí ‘kóòtù’. | That ease the dispensation of justice in all courts. |
| | |
| Ara ohun tó mójútó nínú iṣẹ́ àkóso ètò ìdájọ́ | Part of his achievement in the |
| Ó ra mọ́tò gidi bọ̀ọ̀kù-bọ̀ọ̀kù fádájọ́ yíkáyíká! | administration of justice Is the provision of vehicles for all judges |
| Owó tó ní láárí ló fi ń kówó oṣù fẹ́nìkọ̀ọ̀kan adájọ́, | And he has reviewed the salaries of judges As a way of appreciating their services. |
| Ó níṣẹ́ adájọ́ le! | |
| Ó ti ṣètò ẹ̀yáwó-kọ́lé fún wọn lọ́nà kan, | He introduced a housing loans scheme for them |
| Ọ̀nà ìrọ̀rùn pátápátá ti wọn fi ń sanwó díẹ̀ díẹ̀. | He should take credit for initiating an easy re-payment schedule. |
| Iṣẹ́ tí Bọ́lá Tinúbú ti ṣe | What Bọla Tinubu has achieved in office |
| Kàyà kàyà ló jẹ́, | Is very intimidating |

| | |
|---|---|
| Mo débẹ̀ mo wòran; | I was there and watched |
| Ìmọ̀ àtòye tuntun ló mú wọṣẹ́ ọba, | He brought knowledge and wisdom into governance |
| Àwọn ìlànà àkóso tó mọ́lá Èkó tẹ̀ síwájú, | Those administrative strategies advancing the status of Lagos. |
| Aṣíwájú ti mú wọn bọ̀ látòkè òkun. | Aṣiwaju brought them all from abroad |
| Tó ní bí wọn tíi ṣiṣẹ́ ọba tíṣẹ́ fi í yọ, | Affirming an approach to governance that bears fruits |
| Lábẹ́ẹ Tinúbú nìkan, | Under Tinubu's leadership alone |
| Ìròyìn Èkó tóó ṣe fún gbogbo Naijiria. | Reports on Lagos are newsworthy for all Nigerians. |
| | |
| Bó bá jẹ́ ká fọpọlọ pípé sisẹ́ nìkan, | Talk about applying the intellect |
| Àràbarà ni mo fojú ri – | I have seen wonders |
| Wọ́n tóó mú kọ́gbọ́n – | There is so much to learn from it |
| Wọ́n tóó pa láriwo, | They deserve publicity |
| Mèremère ètò tẠ́síwájú gbé wá, | The important programmes of Aṣiwaju |
| Mímú ló máyé ará Èkó dùn gbọ́ngbọ́n; | Have transformed the lives of Lagosians |
| Bí wọ́n bá ń pariwo Aṣíwájú níbikíbi | That is exactly why they sing his praise all over. |
| Ìdí ọ̀rọ̀ nu un; | |
| Kì í ṣe pé wọ́n ń ròyìn-in rẹ̀ lásán, | They are not talking about him in vain |
| Ó rọ́jú siṣẹ́ dà sílẹ̀. | He has done a lot to merit it. |
| | |
| Àwọn erin lákátabú ìtẹ̀síwájú tó mú wọṣẹ́ẹ̀jọba, | The great progressive ideas that he brought Into the art of governance are innumerable |
| Àìmọye ni wọ́n, | |
| Mímú ló mú wọn lẹ́sẹẹsẹ; | Applying them one by one |
| Àròjinlẹ̀ ọpọlọ gidi sì ni tÀkànbí | Akanbi exhibits the gift of indepth intellect |
| Lásán kọ̀ ló dakẹ́hìndé-gbẹ̀gbọ́n mọ́ kóówá lọ́wọ́, | Not for nothing did he rise to leadership from the rear |
| TAṣíwájú Bọ́lá Tinúbú fi pàpọ̀jù nínú àwọn ọpọlọ tó jíire, | Asiwaju Bọla Tinubu is outstanding among the endowed |
| Kò sígi méjì obì nígbó; | There's only one species of Kola nut tree |
| Tinúbú ti dabàmì òsèlú tó ṣiṣẹ́ tí ò wọ́pọ̀. | Tinubu is a rare politician with unmatched performance. |
| | |
| Iṣẹ́ tí Bọ́lá Tinúbú ṣe nípa àtúnṣe ojú ọ̀nà, | What Bola Tinubu has accomplished on the repair of roads |
| Àti àwọn ọ̀nà tuntun-tuntun tó náwó sí, | And the many new roads |
| Wọ́n tóó mú kiní sì gan-an ni: | Deserves profound appreciation |
| Ọ̀nà Àjá lọ sÉjìgbò, | The road from Aja to Ejigbo |
| Kí gbogbo o wá dé bẹ̀ ká wàrà tó dá; | Let's all be there to behold wonders he performed |
| Ká tún dé Agbóròókò tààràtà maa lọ sígbó Elérin, | Let us visit Agboroko right away, en route Igbo-Elerin |
| Ọ̀na ìyànà Ibà tó gba LASU lọ, | The road from Iyana Iba to LASU |

| | |
|---|---|
| Èèyàn ò ní í ri kó má ṣàdúà. | No one will pass through without prayer of acknowledgement. |
| Ẹnikẹ́ni tó bá mọ òpópó Awólọ́wọ̀ lágbègbè Ìkòyí níjọ́sí, | Whoever knew the old Awolọwọ Way in Ikoyi |
| A fẹ́ kẹ́ ẹ lọ wàrà tÁṣíwájú fi títì náà dá, | Should go and see the feat that Asiwaju has performed on it |
| Fún dídán tó ń dán, | |
| Fún ti fífẹ̀ sí i ; | For its smoothness and its new size |
| Àti gbogbo òdòdó tÁṣíwájú ní kí wọn ó gbìn sí bèbè ọ̀nà. | And its beautification with flowers as ordered by Asiwaju! |
| Bẹ́ ẹ bá ti mòpópó Akin Adesọla tẹ́lẹ̀ níjọ́sí bó ti rí, | If you knew the old Akin Adesọla Road as formerly was |
| Ṣe bí níṣẹ́ lẹ bá jẹ́ a sèbẹ̀wò sí lọ; | Then let's pay an inspection visit to the place |
| Bó bá ṣe pé bí i tìjọ́sí ló tún rí, | |
| A fẹ́ kẹẹ sọ: | We want you to see if there has been no change. |
| Adéọlá Ọ̀dẹ́kù ni ẹ fàbọ̀ sí, | Then come to Adeọla Ọdẹku |
| Ká tún dé pópó Onikan wò. | And move further to Onikan Road. |
| Bá a bá wá rágbègbè ọrọ̀ ajé, | If we now move to the commercial centre |
| Ká dé pópó 'Broad Street'; | Let us visit Broad Street |
| Àní sẹ́, | Just to see how it has been tarred |
| Bó ti ṣe jẹ́ fífẹ̀, dídọ̀dà-sí-lójú; | And also widened |
| Bá a bá jọ gbabẹ̀ dágbègbè ìta-Tinúbú, | From there we can then get to Tinubu Square |
| A tún fẹ́ẹ́ wo bẹbẹ tÁṣíwájú ṣe lórí wọn nị; | To behold Asiwaju's feat in all the places |
| Gbogbo Tafawa Balewa títí tó fi dé Marina. | From Tafawa Balewa down to Marina. |
| Àwa tá a mójú ara wa rọ̀nà Ìpágodó-Ògòlònto, | Those of us who have been to Ipakodo-Ogolonto, |
| Àwa la mọun tÁṣíwájú fowó ṣe | Know what Asiwaju has done with money |
| Ònà Ẹpẹ́ sí Lẹki kọjá à ń ròyìn ní sòkì làsán, | We cannot just describe the Ẹpẹ-Lẹki Road in few words |
| Ẹní bá le mójú re bẹ | Whoever has been there |
| Yóó ròyìn gbogbo wọn bí wọn bá ti rí gan-an; | Can tell of its state |
| Ọ̀nà Ọtẹ́núnbí-Ògìdán gbọ́ títúnṣe, | Otenubi-Ogidan Road has been rehabilitated |
| Yíyọ̀ ló ń yọ̀ kùlùlù. | And it is now very smooth. |
| Òpópó ńlá Ọba Sẹkúmádé ńkọ́? | What about Ọba Sẹkumade Road? |
| Bí a dé Tòkunbọ̀ Adémọ̀lá ńkọ́? | And Adetokunbọ Ademọla? |
| Wọ̀n fi ń yé gbogbo wa pówó ni ń táraa ṣe; | They show us the change that money can bring |
| Ọ̀nà Ìgandò ńkọ́? | What of Igando Road? |
| ṢÁgege 'motor road' ò tóó kí Bọ̀lá sí? | Should we not thank Bọla for Agege Motor Road? |
| Ṣé Tinúbú fọmọ yọ, àbí ò fọmọ yọ? | Has Tinubu excelled or not? |
| Òun ni mo sì fi béèrè wípé kíló ń ṣe sánmọ̀, | That is why I wonder why the clouds |

| | |
|---|---|
| Tóòrùn ò ràn? | Have not allowed the sun to shine. |
| | |
| Ìjọba Tinúbú tún ṣe ọ̀nà Itirẹ | Tinubu administration also did the Itirẹ |
| Lọ sí Lawanson títí dOjuẹlẹgba | Lawanson Road down to Ojuẹlẹgba |
| Àtọ̀na tó njẹ́ Kudi Abiọla tó wà l'Ọrẹgun; | Including the Kudi Abiọla way at Ọrẹgun |
| Ó kúkú tún ṣe Jakande re Isẹri; | He also did the Jakande-Isheri Road |
| Ọ̀nà ọ̀jọ́ Alábà, ọ̀nà Ìjegun, | The Ojo-Alaba Road and the Ijegun Road |
| Ẹnì kan ò lè pé e ní náwósi kọ, | No one will deny that huge expenses were involved |
| | |
| Kí gbogbo wọn ó tóo dùn un gba. | To make them smooth and motorable. |
| | |
| Lábẹ́ẹ Tinúbú, | Under Tinubu, workers are very |
| Gbogbo òṣìṣẹ́ ni wọ́n ń gbádun tó kín n la! | comfortable |
| Gbogbo òṣìṣẹ tó ń sisẹ́ pẹ̀lú ìdùnnú lásán kọ́ | It's not for nothing that the workers are happy |
| | |
| Aṣíwájú ló mú wọn nínú dùn– | It's because Aṣiwaju has made them glad |
| Wọn ò fara hẹṣẹmọ nibikibi; | They are no more demoralized and lazy |
| Òsiṣẹ́ ń gbowó oṣù ó sì ń tóó ná, | They are earning enough for their labour |
| Owó tún ṣẹ́kù lápò! | To the extent that they can save some money! |
| | |
| Lábẹ́ẹ Tinúbú | Under Tinubu, workers can testify that they |
| Gbogbo òṣìṣẹ́ ni wọ́n mọ̀ wípé | are already working with a leader |
| Wọn ti ń bólórí ṣiṣẹ́, | |
| Wọn ò rírúu tẠ́síwájú nípínlẹ̀ Èkó rí, | In Lagos State, they never had anyone as good as Aṣiwaju |
| | |
| Wọ́n ń nílé lórí, | They enjoy good housing |
| Wọ́n ń ra mọ́tò, | They can afford to own their cars |
| Wọ́n ń tún mọ́tò wọn ṣe | And even repair them; |
| Ó fowó kúnwó fún wọn, | He increased their salaries |
| Wọ́n bọ́ sínú ayé tuntun. | They are witnessing a new era |
| Gbogbo òṣìsẹ́ ló ti ń gbádùn gbáà! | Every worker is in comfort! |
| Àwọn òṣìsẹ́ ti wọ́n ń gbẹ̀bí tó jìnnà síbi isẹ́, | Those living far from their places of work |
| Gbogbo wọn ò ti ẹ̀ dààmú mọ́tò wíwọ̀ mọ́ rárá, rárá | No longer worry about transport problems at all |
| Pánúmọ́ ń kó wọn lọ, kó wọn bọ̀ lọ́jọ́ kọ̀ọ̀kan ni, | As buses now move them about daily. |
| Gbogbo òṣìsẹ tó pẹ́ lẹ́nu iṣẹ́ ìjọba, | Those with long years of service |
| Àìmọye ẹ̀bùn ìwúrí ló ń fún wọn, | Get rewards for their dedication |
| Tí wọn sì ń yọ̀ sẹ̀sẹ̀. | And they are very happy indeed! |
| Aṣíwájú tó bá lè maa bìkítà fún gbogbo òṣìsẹ́ abẹ́ ẹ̀, | A leader that can care for all workers under him |
| Béèyàn ò sẹ̀sẹ̀ wí ó tóó pọ́nlé; | Deserves commendation and honour |
| Bọ́lá Tinúbú gbayì lọ́jọ́ gbogbo ẹni tó jólórí fún, | Bọla Tinubu commands the respect of the people he leads |
| Ohun tó mú kọ́gbọ́n ni fún gbogbo wa; | We all need to learn from this |

Yàtọ̀ fún gbogbo òsìṣẹ́ tó ń tọ́jú

Ó tún tóbi lọ́wọ́ àwọn ènìyàn ìlú bíntín kọ́

Aṣíwájú tó ṣe é mú yangàn ní tòjò-tẹ̀ẹ̀rùn.

Àìmoye Mùsùlùmí ló ń rán lọ sí Mọ́kà
lọ́dún lọ́dún
Ara ohun tó fi ń níyì náà rèé.

Ká wí ká gbọ́
Ẹni tó mọnúrò jọjọ sì ni,
Àìmọye òṣìsẹ́ ló ń rán lọọ Jerusalẹmu
lọ́dún lọ́dún
Bẹ́ ẹ rí wọn ẹ lè máa béèrè àlàyé,
Kẹ́ ẹ gbọ́ làbáárè.

Ẹni tó bá lọ sóko ẹja
Pàtàkì, èyí tÁṣíwájú bá wọn dá sílẹ̀
Tó ń bẹ ní agbègbè Ìkòròdú
Bó bá délé,
Gbogbo ohun tó bá rí níbẹ,
Kó ròyìn káráyé ó gbọ;
Ibi tí wọ́n ti ń tolẹ̀ fẹ́ni kọ̀ọ̀kan tó fẹ́ sin ẹja:
Aṣíwájú Bọ́lá Tinúbú fikòkò sebẹ̀ oyin
mọmọ ẹja
Àfàìfẹ́ jẹja tútù ló kù.

Gbogbo ẹni tó bá fẹ́ ṣiṣẹ́ òkòwò ẹja,
Ànfààní dé, iṣẹ́ ló wà ńlẹ̀ yí fún kóówá,
Ẹ lọ gbọ́ bí wọ́n ṣe ń tolẹ̀ fọ́lọ́sìn ẹja;
Kóníkálukú lọọ bèèrè àlàyé –

Nílé iṣẹ́ ètò ọ̀gbìn Ìjọba Èkó l'Álausa
Oore ló kúkú wà ńbẹ̀.

Bí wọ́n bá ní ká sọ nípa ètò ẹ̀kọ́
Tó múná dóko tó yè kooro
Ìjọba Tinúbú ló ṣe bẹbẹ ńlá-ńlá,
A ti fojú rísẹ́ tó ń ṣe níbi gbogbo;
Ibi àwọn ètò ìtẹ̀síwájú ti báṣẹ ẹ̀kọ́ Èkó dé
Dájúdájú sísọ lẹ́nu ò tó ká le fojú rí wọn,

Àìmọye àrà tÁṣíwájú dá lórí ilé ẹ̀kọ́ pàpọ̀
jù.

Apart from public servants that he caters
for
Members of the public also hold him in
high esteem
He is a leader that one can be proud of at
all times.
He sponsors many Muslims to Mecca
yearly
Which accounts for his popularity.

And he is a thoughtful person
He sponsors numerous workers to
Jerusalem on pilgrimage every year
You can get the details from those
concerned

Whoever visits the special fish farm

That Aṣiwaju established around Ikorodu
Should talk about everything he sees
So that people may know.

That is where fish farmers buy fingerlings
Asiwaju has made it possible for all to
enjoy fish
Only those without appetite
For fresh fish will be left out.
Those interested in fish farming
Now have limitless opportunity for
employment
Go and enquire about fish farming
Make enquiries at the Lagos State Ministry
of Agric, Alausa
There are benefits in so doing.

Talking about sound education,

Tinubu's administration has done great
wonder
We have seen his deeds everywhere
It is better to see the progress
Done on education in Lagos than talk about
it
The changes that Asiwaju has brought to
Education are too numerous.

Ọwọ́ tí Bọ́lá Tinúbú fi gbá gbogbo ètò ẹ̀kọ́ mú,
Bó bá ṣe pé tìjọba Èkó ni;
Ìlànà opọlọ tó múṣẹ́ yọrí sí rere ni;
Àjànbàkù kankan ò sì wọbi ètò ẹ̀kọ mọ́,
Pínpín ló pín wọn nísọ̀rí, ìsọ̀rí –
Tíṣẹ́ wá yágiiri;
Ẹni tó bá kúkú ti lọ́pọlo ètò níí ṣàṣeyọrí sí rere,
Ìlànà tí Bọ́lá fi májẹ̀mú ètò ẹ̀kọ́ lé lórí
Ó ti fi múná ẹ̀kọ́ jó.

Ìgbìmọ̀ kan ló rọra gbéṣẹ́ àti ta ètò ẹ̀kọ́ jí le lọwọ́
Wọ́n já fáfá ní lé iṣẹ́ ètò ẹ̀kọ́, bíntín kọ́;
Gbogbo bíṣẹ́ ṣe ń lọ
Kò ṣẹ̀yìn àmójútó àtàṣẹ Aṣíwájú níbikíbi.
Òhun lètò ẹ̀kọ́ bá ṣe bẹ́ẹ̀ tó fi gòkè àgbà

Èkó wá dibi tí wọ́n ń wò tí wọ́n fi ń ṣètò
Ọ̀tọ̀ ni tàwọn ilé-ìwé
Tó ṣe pé wọ́n ti pa kí Bọ́lá ó tóó dé,
Tó ṣe pé ní kánkán ò yà símọ̀ rárá;
Aṣíwájú bojú wobi ètò ẹ̀kọ,
Ó sì bomi rin gbogbo koríko gbígbẹ
Gbogbo ẹ̀ gbògbò ẹ̀ ló tún ṣe tí wọ́n wà láàyè!

Ọ̀tọ̀ làwọn ibi tÁṣíwájú kọ́ ilé ìwé tuntun-tuntun sí,
Ká débẹ̀, ká wàrà tó mówó dá lọ́tọ̀
Bí wọ́n ti ṣe gbáfẹ́ tó,
Bí wọ́n ṣe rí mère-mère,

Iṣẹ́ tó jọ ni lójú ga dọ́ba ni,
Kò sí yàtọ̀ sí bí wọ́n ti ń kọ́ tìlú Òyìnbó,

Ó kúkú fẹ́ẹ̀re fún gbogbo ẹ̀dá ènìyàn.

Aṣíwájú Bọ́lá Tinúbú, o pọ̀ jù wọ́n lọ,

Lọ́nà kọnà lomi ọgbọ́n ń bá wọnú ajere,

Ìlànà ìjọba tiẹ̀ ò sì múrọ̀ lọ́wọ́;
Lásán kọ́ ló gbẹ́rù náà dórí,

Bọla Tinubu gives priority to education
The government of Lagos has a plan
That has proved to be excellent
There is no room for mediocrity
In the system any longer
He has reorganized them for smooth operation
Only those versed in administration achieve success
The plan on which Bọla built the new educational system
Has stirred a revolution in the sector.
He simply mandated a committee to restore the system
And they are so competent
The progress being recorded all over
Is under the keen supervision of Asiwaju
That explains why education has experienced a push
Lagos has now become a pacesetter.
Even schools that were neglected before
Bọla's tenure
Are no more the same
Asiwaju attended to educational revival
And watered all the withered grasses
And he brought them all back to life!

Asiwaju built new schools in separate locations
It's good to be there and see what he has done with public funds
We can then see how modern and decent they are
The job is impressive
And it is not different from the standard abroad
As he wants the best for everyone.

Asiwaju Bọla Tinubu, you have surpassed your competitors!
Wisdom finds its way by many channels into the perforated pot.[5]
His government has no room for falsehood
It's not surprising he has succeeded

| | |
|---|---|
| Ẹni Ọba mímọ́ bá ń bẹ lẹ́yìn-in rẹ̀, | Anyone who enjoys the support of the Almighty |
| Dandan ni kó dádé oríire; | Is bound to wear the crown of success. |
| Àṣeyege tiẹ̀ ò ṣàdéédé wáyé | And his success is not by accident |
| Ọba yáárábì ló wù. | It's only the pleasure of Almighty God! |
| | |
| Ọba mímọ́ ló ń kọ́ ọ lati mọ̀ ọ́n ṣe, | The Holy God teaches him |
| Èmi ò mọ un tí wọ́n fi ń bínú olóríire | That is why I cannot quite understand<br>Why some people are envious of his success |
| Èmi ò mo un àjànàkú ń fojú ìṣẹ́ wọ̀bọ sí | I cannot understand why the elephant underrates the monkey |
| Bóyá ló yé wọn pọ́bọ ò tọrọ jẹ; | They may not know that the monkey has never lacked |
| Ẹni tó ṣáájú ti lọ níwájú-wájú, | The advancing one has covered a long distance |
| Kíló ń ṣe wọ́n sariwo? | Why are they making a noise? |
| Èwo làròyé ọ̀tẹ̀ tí wọ́n ń ṣe lórí ọmọ ìyá-lọ́jà? | Why are they making a rebellious noise<br>Concerning the son of Iyalọja?[6] |
| | |
| Aṣíwájú Bọ́lá Tinúbú fọmọ yọ, ẹ̀gàn kọ́; | Asiwaju Bọla Tinubu excelled<br>There is no doubt about it |
| Gbogbo ẹranko tó fẹ́ ṣebí ọ̀bọ tàkìtì – | Those who cannot walk are desperate to run |
| Òkìtì àtadojúdé ni wọ́n ta! | Why are they unnecessarily troubling themselves? |
| Àìmọ̀wọ̀n ara ọ̀pọ̀lọ́ tó gbéra tó janra rẹ̀ mọ́lẹ̀! | Animals that imitate the monkey in somersaulting<br>End up falling flat on their faces!<br>The frog in immodesty hit itself on the ground! |
| | |
| Ọgbọ́n tí Bọ́lá Tinúbú gbọ́n tó fi ń ṣàkóso, | Bọla Tinubu administers with wisdom |
| Òye gidigidi òun ìmọ̀ àmọ̀lo, | Insight and applied knowledge |
| Ọ̀pọ̀ ìrírí tó ti ní látìlú òyìnbó tó gbé wálé | A lot of experience gathered abroad |
| Ká tó wá sọ nípa làákàyè àtọpọlọ tó jíire; | Not to talk of knowledge and brilliance |
| Ọ̀pọ̀ nínú ọmọ adúláwọ̀ tó dángájía bíi irú tÀkànbí | Few Africans are as qualified as Akanbi |
| Bírọ́ bá bẹ ńbẹ̀ ló kù. | Except we want to tell a lie. |
| | |
| Akọ́ṣẹ́-mọṣẹ́, mọyíóó-mọyíóó, aláàkóso! | Technocrat, Chartered Accountant, Administrator, |
| Ẹni afọ̀lọ̀rọ̀ lórí iṣẹ́ ìlú, ọ̀mọ̀wé tó dá ní tọ́ Alárọ̀jinlẹ̀, | Accomplished expert in public affairs, outstanding intellectual, |
| Akin ọmọ nínú ọlọ́pọlọ, | Deep thinker, political consultant |
| Ayẹ̀wé owó wò gidi tàárà táárá | Outstanding auditor; |

| | |
|---|---|
| Akọni alárìsikí ìmọ̀! | The valiant and knowledgeable one! |
| Bẹ́ ẹ dé gbogbo ìlú Amẹ́ríkà níbi tó ti gboyè ńlá-ńlá<br>Ó lórúkọ níbẹ̀ díẹ̀ kọ́ rárá,<br>Ẹni tí ń jẹ́ Bọ́lá Tinúbú gbayì nílẹ̀ èèyàn funfun;<br>Alákíkanjú ọmọ níí jẹ́ níbikíbi,<br>Pabanbarì òṣèlú ni láyèkáyè, lọ́jọ́kọ́jọ́<br>Aṣíwájú ni nínú ẹni iyì lórílẹ̀-èdè! | He is known all over America where he studied<br>He is indeed well known there<br>The man called Bọla Tinubu is respected across the land of the white<br>He is prominent everywhere<br>He is an uncommon politician of all time<br>And is no less respected among dignitaries in the nation. |
| Aṣíwájú!<br>Bọ́lá!<br>Tinúbú!<br>Arákùnrin ìyanu tíí gbéná wojú ẹbọra! | Aṣiwaju!<br>Bọla!<br>Tinubu!<br>Wonderful man, the-one-who-looks-the-monster-in-the-face! |
| Àkànbí taagun máláṣejù lọ́wọ́ tán;<br>Wọ́n sáré, wọ́n bá a lọ́na,<br>Wọn ò mọ un tí wọ́n lè rí fọmọ ṣe | Akanbi defied the extremist who ran up to him<br>And they were at a loss as to what to do with him |
| Ọkùnrin mẹ́ta ọ̀tọ̀ọ̀tọ̀ Èkó tíí húkọ́<br>Tíí já wọn láyà ní tòjò tẹ̀ẹ̀rùn! | The brave man of Lagos who coughs<br>And intimidates at all seasons! |
| Ẹni tó gbọ́n sásá ló lè rísẹ́ ìjọba Èkó se,<br>Ẹnìkan dìẹ̀ dìẹ̀ ò ṣe é fàṣẹ ìjọba Èkó lé lọ́wọ́ | Only the very brilliant can govern Lagos<br>No dull and sluggish person can govern Lagos |
| Un ló fi yan Babátúndé Fáṣọlá<br>Ẹni ìlú ń dúró dè ni;<br>Ibi tÁṣíwájú ṣisẹ́ ìjọba Èkó dé<br>Fáṣọlá ni ó ṣèyókù.<br>Bó ṣe ti ṣe mímójútó ni, bó ṣe tìmọ̀ àkóso | That is why Babatunde Faṣọla[7] is fit for it<br>He is the one that the people are waiting for<br><br>Faṣọla is the one to take the baton<br>From Aṣiwaju in the governance of Lagos.<br>Whether it is in project management or administration |
| Béèyàn bá ń wá akọni ọ̀jọ̀gbọ́n,<br>Akínrọ́pò tí ó ṣètò tó mọ́yán lórí, | If you seek a brave and intelligent person<br>An ideal successor with vision and thoughtful plans |
| Babátúndé Raji ni ẹ dìbò yàn sórí àga;<br>Èèyàn tí ò dìbò fún Fáṣọlá,<br>Olúwa rẹ̀ ló fẹ́ fibò ṣòfò!<br>Ìka tó bá tọ́ sínúumú lèèyàn fìì remú, | Elect Babatunde Faṣọla into power<br>Those who do not vote for Faṣọla have wasted their votes! [8]<br>We pick the nose with the appropriate finger. |
| Taa ni ò mọ̀ pó di dandan ká báráàlú sọ̀rọ̀ òtítọ́?<br>Ẹni Tinúbú bá le fi ṣọ̀gá àgbà àwọn onísẹ́ ọba, | It is imperative that we tell the public the truth<br>Whoever was qualified to serve Tinubu as Chief of Staff |

Kò di̇gbà tá a bá sẹ̀sẹ̀ pó jáfáfá, ó mú yányán –
Kóówá ló yẹ kó ti mọ̀ bẹ́è.

Does not need further recommendation
That he is efficient and competent
Everyone ought to have known that.

Babátúndé Fáṣọlá tẹ́ ẹ rí un,
Èèyàn kan takuntakun tó kájúuṣẹ́ takuntakun ni;
Gbogbo ọ̀tọ̀ọ̀kùlú ló fọwọ́ sí yíyàn rẹ̀ pátápátá
Atóómú-delé, akin-ogun –

Ọ̀jọ̀gbọ́n nínú Ìjọba ṣíṣe ni;

Ìfà lÈkó fẹ́ kó bi wọn bá yanrú ẹ̀ ní gómìnà.

Babatunde Faṣọla
Is a dynamic and competent fellow
Whose choice enjoys the endorsement of prominent people
He is a person one can be proud of, a veteran of battles
He is an adept in the business of governance
Lagos will be fortunate if he is elected Governor.

Ọkọ Abímbọ̀lá ti mọ gbogbo ọ̀rọ̀ Èkó tinú tòde
Kì í ṣẹni tó jẹ́ pe bó bá dépò, yó sẹ̀ṣẹ̀ bẹ̀rẹ̀ síí kọ́ṣẹ́,
Lọ́gán tó bá ti dórípò, yóó kàn maa báṣẹ́ lọ ni
Èkó ò sì leè màlá rárá, pé bóyá Aṣíwájú kúrò nípò.

Abimbọla's husband knows the affairs of Lagos inside out
He is not a person who will be learning on assuming office
He will just swing into action straight on assumption
And Lagos will not even know that Asiwaju has vacated office.

Babátúndé Fáṣọlá tẹ́ ẹ rí un
Èèyàn yẹpẹrẹ kọ́ rárá rárá
Olọ́pọlọ gan-an ni;
Ara àwọn àgbà ọ̀jẹ̀ nínú 'lọ́ọ́yà' nílẹ̀ yí ló jẹ́
Lábẹ́ẹ Tinúbú ó kó oníṣẹ́ ọba jẹ̀ fọ́dún mẹ́jọ!

The man Babatunde Faṣọla
Is not a mean man at all
He is extremely intelligent
He is one of the senior advocates of this land
Under Tinubu, he led public servants for eight good years.

Gbogbo òṣìṣẹ́ gbọ́ pó fẹ́ jẹ Gómìnà,
Gbogbo òṣìṣẹ́ ń dúpẹ́,
Fáṣọlá ni ó wà nípò.
Èkó ò níi bàjẹ́ láéláé!

All workers were glad to hear of his gubernatorial ambition
They were glad to know he would take over.
Long live Lagos!

Bórí bá bá wa ṣe é, bẹ́ ẹ bá fi gbàmọ̀ràn,
Tó jẹ́ pé Fáṣọlá l'Èkó dìbò fún,
Káyé ó máa túbọ̀ rọrùn sí ni;
Níbi Aṣíwájú Bọ́lá Tinúbú ti ṣiṣẹ́ dé,
Kó maa báṣẹ́ lọ ni;
Gbogbo òye ìmọ̀ ìjìnlẹ̀,
Ìròrì tuntun tó ní lọ́kàn,
Tó fi fẹ́ ran gbogbo Èkó lọ́wọ́,
Kó wá mú wọn wúlò ló kù.

If we are fortunate enough that you take this counsel
So that Lagos votes for Faṣọla
Then things will further get better
He would just take off from wherever Bọla Tinubu ended
So that he can apply all his wisdom, knowledge and new ideas
To help in the governance of Lagos.

| | |
|---|---|
| Aṣíwájú Bọ́lá Tinúbú ròyìn-in rẹ̀ fún mi gan-an, | Asiwaju Bọla Tinubu told me a lot about him |
| Tó jẹ́ póríì mi sì ń wú; | To the extent that I became impressed |
| Bó ṣe ti sẹ mímúrasí gidigidi, | He talked about his uncommon dedication |
| Ìwà òtítọ́ ìwà òdodo; | His honesty and integrity, |
| Ìwà àkóyawọ́ ohun èrò ìtẹ̀síwájú, | His openness and progressive ideas |
| Ó ní wọ́n ń bẹ lọ́wọ́ rẹ̀ tó pọ̀. | Which he manifests in abundance. |
| | |
| Ìdí rẹ sì nì yìí; | That explains |
| Tó fi jẹ́ pè béèyàn ò dìbò fún Fáṣọlá, | Why for anyone that does not vote for Faṣọla |
| Bónítọ̀hún jábọ́ sí kànga, ó kúkú yá | It would have been better to throw the ballot paper into a pit latrine |
| Babátúndé Fáṣọlá ni ẹ dìbò fún, | All good-natured people should vote for |
| Ẹ̀yin olóríire gbogbo, | Faṣọla |
| Èkó ò ní í bàjẹ́ láé láé | Long live Lagos. |
| Mo fẹ́ kẹ́ ẹ f'ìbò sàmín | Say amen to this symbolically with your vote! |
| Ká gbé Fáṣọlá dépò ká má ba à fibò ṣòfò, | Let us enthrone Faṣọla and not waste our votes. |
| A kì í ṣe é mọ̀: | In case of any enquiry |
| Bí wọ́n bá bi yín léèrè wí pé: | As to who composed this exemplary song |
| Taa ló korin ewì tó lápẹẹrẹ | Tell them that Lanrewaju did – |
| Kẹ́ ẹ sọ pé Lánrewájú ni– | |
| Ọánrewájú Adépọ̀jù Àkànmú tó ḿaa ń forin ewì dárà! | Ọlanrewaju Adepọju Akanmu who does wonders with *ewì*.[9] |

**REFERENCE**

Adepọju, Lanrewaju (2007) *Tinúbú F'ọmọyọ* in *Ẹ̀yin Ọmọ Nigeria* (Side B). LALPS 169. Ewi Hit Hot Series 64. Ibadan: Lanrad Records.

---

1 The play on the title of Aṣiwaju (leader) here is apt. It is a way to affirm that the title itself is fitting.

2 Great Britain.

3 Massive buses for which Lagos was known. The buses came to embody the chaos of living in the city.

4 This is Tinubu's personal *oríkì*.

[5] The Yoruba use the perforated pot for a variety of purposes – for instance, roasting and sieving. It becomes a metaphor for the various sources of knowledge that the poet attributes to Tinubu in the world of the poem. The immediate reference is to the ease with which water enters when the pot is dipped, suggesting Tinubu's dynamism and ability to gain knowledge from various sources.

[6] Tinubu's mother was a leader of market women. This is therefore a reference to him.

[7] Babatunde Faṣọla, a Nigerian Senior Advocate of Nigeria, served as chief of staff to Bọla Tinubu when he was governor of Lagos.

[8] Faṣọla was elected governor of Lagos for a four-year term in 2007.

[9] This is a variant of Adepọju's closing formula.